# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. III. No. 114. SATURDAY, SEPT. 20, 1924. Fourpence.

**DURO THOMAS.**

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc."**

---

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

OYINBO **J. F. SICK**

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orişirişi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita:—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Waji, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Òlokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumădan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa; A ni nkan wọny fun tita:—

Ikoko taba Onigi, Jigi, Aṣọ Aran, Ẹrọ agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Àjàrà (*Wine*), Awọn onjẹ Ipanu, aṣọ iṣ'ọṣọ, Ẹrọ ere ọmọde, Ohun Ọṣọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Maşini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile owo ni:— Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

# LEVER STORES LTD.

## No. 1, LAGOS.

# OLOWO S'OKE D'ILẸ

A ni oriṣiriṣi ọja fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

A nta awọn ọja wa ni :—

**3d. 6d. 9d. 1s.**

A nṣi ilẹkun di agogo kan ọsọsan Thursday.

A si nti ilẹkun ni agogo meje alalẹ Satide.

Editor :—
ADEOYE DENIGA,
*Offices*: 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

A-ṢEYI Ṣ'AMỌDUN O, ỌMỌ ALAKẸSAN.

Ni *Tuesday* (Atalata) ọsẹ yi ti o jẹ ọjọ kẹrindilogun oṣu yi, ni ọrẹ wa Ọgbẹni T. I. Kester Olori, di ọmọ ọdun mejilelogoji gbako: bi o ri jagun wa na, bi ọmọ ọgbọn ọdun pere lori; iba fi ọna Ajidewe rẹ han wa nkọ o a ba yọ yọ. Ṣugbọn ẹnikeji, nkan mimu ati ṣerẹkẹṣin wa nkọ, tabi awa papa ko ni gbadun ọjọ ibi na ndan? Aṣeyi ṣamọdun o, Ẹlẹpa-iṣana Kiniun Kotu, ọmọ Alafin Ọyọ, a bẹrẹ l'oji!!!

IGBAGBE KO LOGUN.

Ẹjọ *Jury* gbe wa lọ si Kotu Ebute Mẹta ni *Tuesday* ọsẹ yi, lati lọ sọ kilopa Awamotọ kan ti o njẹ Abudu Karimu ni lọlọyi, ninu ẹri ti Dokita Oyinbo kan jẹ, o fi han kedere pe ọkọnrin na ṣeṣi fi Motọ rẹ na kọlu nkan ni, tobẹ ti on papa fi ṣèṣé, ti o si di ẹni ọrun.

Ninu awọn ti a fi orukọ Ọba *King* pe lọ si *Jury* na ni Ọgbẹni S. A. Ṣogbẹsan Atotiletọ, Ọgbẹni Bada, Akọwe Agba ti awọn *Lawyer* Alakija, Ọgbẹni Saka Bakare, Ajirera, awa papa, ati Ọgbẹni kan ti orukọ rẹ sa-wa-nja. A pe Ọgbẹni J. A. Oṣodi pelu, ṣugbọn anu ṣe ni pe Adajọ ko ri lẹhin igbati a pe e leralera bi ẹmẹfa. Adajọ si bu pọun meji fun u (£2) ni sisan; anu Alagba wa yi ṣe ni gidigidi, nitori ọja ti ko ra ti a si ni ki o sanwo rẹ yi, a ro pe boya igbagbe lo ṣe, ṣugbọn bẹ si ni a mọ Adajọ Kotu Ebute Mẹta ni oninure, ti yio mura tan lati foriji Ọgbẹni wa yi, ti o ba sọ ti ẹnu rẹ pẹlu ẹbẹ.

AWỌN IYA-AFIN GBA IṢẸ "OMI ẸRỌ" WIWỌN.

Orukọ awọn obinrin ti awọn Munisipa gba lati ma wọn "omi ẹrọ" ni Ido si awọn obinrin ẹgbẹ wọn ti nkọja lọ lati Eko si Ebute Mẹta niwọnyi:—Matilda Taylor, Remi Goyea, Mrs. Shepherd, Mrs. Crency; a gbọ pe pọun meji-meji (£2) ni owo wọn loṣoṣu titi iṣẹ na yio fi pari.

AKAPO IJỌ BETẸL, O KU ORI'RE!

Ni arin isin owurọ ni Ijọ Bẹtẹl l'Eko lọjọ isimi to kọja, Alufa Alabojuto J. A. Lakeru ni orukọ gbogbo Ijọ yi ta Ọgbẹni D. J. Johnson ti "Ile Olufumi" Opopo Igboṣere l'ọrẹ Bibeli nla kan ati Apo Owo ti o dọṣọ fun õtọ'nu ti o fi ṣe iṣẹ rẹ gẹgẹ bi Akapo Ijọ na fun ogun ọdun. Ọrọ iwuri niba ṣoki ti o ti ẹnu Alabojuto jade lọjọ yi ki o to fi awọn ẹbun na le Ọgbẹni Johnson lọwọ niye lori lọpọlọpọ, bi aṣa imu lo si ka Ijọ lara. Iwasu Alufa Ijọ lọjọ yi lati inu Ihinrere ti *Matteu* 25: 21 ko ṣe rọti s'apakan. Ki a ba le fi iranti si ọjọ yi Ẹgbẹ Igbimọ Ijọ pesẹ si ile Akapo wọn ni 8ṣalẹ; lẹhin ti a si ti gba aworan tan, nkan ṣ'ẹnu're. A ba Ọgbẹni wa ti a kọjusi ṣe li ore yi yọ.

INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.

Ṣaṣa enia lo ma mọ pe Ijọ Ọmọ-ibilẹ (*U.N.A.*) ti Eko nibi nda bira miran ninu ilọsiwaju wọn nipa ina Manamana ti nwọn gba si Ṣọṣi wọn ni lọlọyi; a si gbọ pe ọkan ninu *Member* ibẹ ni ki awọn *Member* ẹgbẹ on to ku da on da inawo gbigba ina na si Ṣukuru awọn ọmọde ti o wa l'ẹgbẹ Ṣọṣi na pẹlu; a tanma pe laipẹ, ina na yio di lilo fun t'ewe t'agba Ijọ.

Nję :—

Ę ma yọ n'nu 'ṣẹ rere
Ẹnyin Ijọ t'awa
*Egbe* :—Ẹnyin Ijọ t'awa (4)
Ę ma yọ n'nu 'ṣẹ rere
Ẹnyin Ijọ t'awa.

AJINDE ARA A MA JẸ FUN Ọ, SALAMỌTU IYA ẸGBẸ ARẸMỌ ABIBU OKI BALOGUN.

A gbọ pe o ti fẹ diẹ si Salamọtu ọmọ Abibu Oki Balogun, ọmọ pẹlẹngẹ ẹlẹyinjuẹgẹ, ti opopo Ẹhin-ọgba ni ọsẹ diẹ sẹhin, ṣugbọn a ṣọpẹ gidigidi pe ilọra na ti nfuyẹ lọpọlọpọ; opo nla ni baba rẹ yi jẹ ni igboro Eko, papa larin awọn Janma Musulumi, ati Iya rẹ pẹlu. Ki Baba tubọ ṣemi rẹ siwaju fun wa ko si jẹ ki ara rẹ le.

ẸGBẸ AHMADIA, Ẹ KU AJALU.

Gbukẹ la gbọ iku Ọgbẹni Adamson I. Yakub Baba-ẹgbẹ Ijọ *Ahmadia* ti ilẹ yi ti o ti jẹ ọkan ninu awọn Akọwe pataki ni Ile-ọwọ awọn Oyinbo Ṣabu Ọlọwọ (*G. Gatslchalk & Co. Ltd.*) Ajalu yi ṣẹlẹ ni ile Ọgbẹni na ni Etiko *Street*, ni arọ Alaruba (*Wednesday*) ọsẹ yi; a si fi Mọto gbe oku rẹ lọ si "Igbàlẹ" Ikoyi; Gasa, Ile Aiye, Ile Asan !!!

Ẹ KU A-GBA-SILẸ.

O yẹ ki Ilu dupẹ gidigidi lọwọ alagba wa, Dokita Oguntọla Ṣapara, fun Egbogi titun ti o ṣẹṣẹ ṣe ni lọlọ yi fun sisa Ajakalẹ-arun ode isisiyi bo 'lẹ. Lilo egbogi na l'eyi :—A o fi ṣibi tabili bu u bi ẹmẹrin sinu igo ofifo kan, a o s bu omi tutu si i bi *tumbler* meji, o di mimi-pọ: lẹhinna, a o ma fi pa ara, tabi ki a wọn ọ si aṣọ-lilo, ati si aṣọ-titẹ sori ibusun (*Bed.*) Enia le ra igo kan fi ṣe igo mẹwa fun lilo: ṣile kan pere ni igo egbogi na o si nbẹ fun tita ni 'le Dokita na ni Opopo-Nla (*41 Broad Street*). Awa papa ra igo kan nibẹ: igbadun rẹ ni pipo pọ mọ omi, ko si b' o tiri ni, ṣugbọn ki iṣe mimu rara.

EWO NI TI OFO AGBARA YI?

Anu ṣe ni lati sọ ti ole to ja iyawo Ọgbẹni S. A. Johnson, ọkan ninu awọn Akọwe pataki ti P.W.D. ni'lẹ yi, ti o ngbe No. 28, Agbo Malu: gbogbo aṣọ-ṣẹda, owo, ati oya iyawo na ni awọn "Gbewiri" na gba lọ raurau ni *Tuesday* ọjọ kẹsan oṣu yi: Ọgbẹni Johnson si ti lọ fi ọrọ na han awọn "Amunimuye" ni "Budo" wọn: a gbọ pe awọn nkan ti nwọn ji lọ to oni £10. 8. 9.

BABA ẸBUN MA NPA'LẸ ILE MỌ, ORIṢA MA JẸ A T'ẸNU MI GBỌ !!!

Pẹlu ayọ ati inu didun la fi sọ fun ẹnyin ọrẹ, ojulumọ ati onibara (*customers*) ọrẹ wa Ọgbẹni Akin Adeṣigbin pe Ẹlẹgiri yio gbe'ra ni'lu Ọba ni Satide to mbọ ninu ọkọ *Waheke*: t'on ti awọn Ọgbẹni J. H. Doherty ati German Martins ni yio si jọ wọ'kọ pọ: dide wọn sibi di ọjọ kẹdogun oṣu to nbọ, lagbara Sòkó. Ẹnyin "Abẹyọ" Tika-Tore, ẹ mura giri lati ba ni gbe orin yi kete ti Ọga ba gunlẹ o.

1. Ọkọ *Waheke* to bọ,
Mo ri 'Tunde, Akin temi nikan,
Ọkọ *Waheke* to bọ
Mo ri 'Tunde, Akin temi nikan;
Ẹ kabọ, ku de, ku de o,
Ẹgbọn *Major*,* wa pẹ.
Ẹ kabọ, ku de, ku de o,
Ẹgbọn *Major*, wa pẹ,
Awa yin ẹ.
Ọkọ *Waheke* to
Mo ri 'Tunde, Akin temi nikan.

2. Ijẹṣa ni Sally, o,
Akintunde l'ara Agọ Owu,
Ijẹṣa ni Sally, o,
Akintunde l'ara Agọ Owu;
Akin ṣẹ ti 'dalẹ de, 'dalẹ de o,
Sally f'orupo pọn 'ti,
Akin ṣẹ ti 'dalẹ de, 'dalẹ de o,
Sally f'orupo pọn 'ti,
Iyẹn wu wa,
Ijẹṣa ni Sally, o,
Akintunde l'ara Agọ Owu.

* *Major jẹ orukọ Arinjẹ ti a fi npe Ọgbẹni Oko Adeṣigbin Aburo Ọrẹ wa na.*

(AKIYESI :—Ẹnikẹni ko gbọdọ da Orin yi tẹ sinu iwe miran, ibaṣe Iwe-irohin lai gba 'ṣẹ lọdọ *Editor Eko Akete*:—Ṣugbọn ẹnikẹnji le kọ ọ ni akọgbadun.)

---

Si Oni'we-irohin *Eko Akete*.

Mo juba o.

A dupẹ pupọ lọwọ ẹgbẹ awọn Tunluṣe (*Town Council*) fun ayan wọn nipa Ajakalẹ-arun (*Plague*) to ntan kiri ninu igboro Eko. Gbogbo wa lo ṣa mọ pe aisan yatọ si Ajakalẹ-arun, papa irufẹ eyi to nja lode nisisiyi, adura wa ni pe ki Baba maṣai dawọ ibinu rẹ duro lara wa.

ONIRUNRU OHUN TI ARUN DA SILE.

Anu ṣe ni lati gbọ onirunru iwa aṣeju ti awọn Wolewole miran fi nṣe iṣẹ wọn nipa lilo agidi ati iwa janduku nigbati nwọn ba ni lati gbe alaisan tabi oku lọ si Ikoyi. A ṣe akiyesi awọn Wolewole meji ti gbogbo ilu nkigbe wọn. Gbogbo wa lo mọ pe ko si ẹniti ofin ko le lo, kini ṣe? Ni *Saturday* ọsẹ to kọja nigbati a gbọ iku Oloye Olorogun anu ṣe ni pupọ lati gbọ pe oku rẹ di ti Ijọba nitori arun to wa l'ode yi, eyi ko bi wa ninu bikoṣe ti mọsondọki Wolewole kan ti gbogbo ilu mọ ni enia lasan ti o fa'ju ro korokoro bi ẹnipe ọdọ rẹ ni nwọn kọ kọ ẹgba mọ.

A dupẹ pe oloye yi fi ọmọ sinu aiye ki o to t'ẹri gba'ṣọ. Iwọ ọrẹ mi to nka *Eko Akete* ti a ba ni mọ ọmọran a mọ ọ. Iwọ Wolewole to nhuwa aibikita nitoripe o ro ara rẹ pin, jẹ ki o da ọ l'oju pe ilẹ yio mọ lẹhin rẹ ni'jọ kan; tani yio sọkun rẹ? Ranti pe ẹni kiku ni gbogbo wa, Sibẹsibẹ mẹlọ-mẹlọ d'ọwọ rẹ o. "Ẹnu aiye l'ẹbọ."

A tun ṣe akiyesi ohun alebu kan si nipa pe ki a gbe oku tabi alaisan lọ si Ikoyi ki a si ti gbogbo ilẹkun, ka si tun ko gbogbo ara ile lọ. Nipa eyi awọn ọlọṣa ti t'ẹwọ gba iṣẹ lati ma lọ fọ ile awọn ẹnibẹ, ibaṣepe Ijọba nfi enia kan tabi meji silẹ, a nireti pe awọn ọlọṣa wọnyi ki yio raye ṣiṣe jamba yi, a bẹ awọn ẹgbẹ Tunluṣe (*Town Council*) ki nwọn yẹ ọro na wo.

Ẹkẹta ni pe, o ta siwa leti pe Wolewole alagbéré yi lọ fi agbara ṣi ilẹkun oloye Onifila-funfun kan, ẹnyin ara ilu ri ohun ti arun ko wọ'lu, tani ba mọ l'ẹwa ko yan run nigbati aiye wa l'aiye? Iyẹn bẹ.

Tani ninu wa to le fi ọwọ sọ aiya pe yio tẹ on l'ọrun ki ọkunrin kan ma wo idodo aya on, ara iwakiwa ti arun ko wọ ilu niyi o.

Iwọ ti ara rẹ wa ni Ebute Mẹta pẹlu ijaiya kọ ni iwọ fi ngbidanwo lati lọ ri won nibẹ ominu fọ, ẹdọ fo ni, nitoripe *Omi ẹrọ* mbẹ ni ati gun Kereni. Nitotọ awọn ẹgbẹ Tunluṣe (*Town Council*) nsapa wọn lati ri pe arun yi buku, eyi dara pupọ, ṣugbọn awọn miran nkọ? Kaka ki nwọn ṣe pẹlu anu nṣe ni gbogbo wọn nṣore kiri pẹlu ihalẹ ọrọ pe "awa lo ndun ninu igo."

Ẹnyin ara ilu, ẹ jẹ ki a ṣe ara wa ni'kan ki a mura lati ran ara wa lọwọ ni ọnakọna ti Ọlọrun ba fun wa.

Njẹ mo fi Ogede kekere yi fun gbogbo ẹnikẹni ti o ba fẹ:—

Olugbode (3)
Aboribẹmbẹ (3)
Emi ọmọ Ọrunmila lo ji
lo nfọhun tantan ki ọ
Iku fo mi da loni
Arun fo mi da loni!

Ẹnikẹni ti o ba ji ti o si nka ọfọ yi yio yọ ninu ewu iku ode yi, ọpọlọpọ yio wipe ṣe Onigbagbọ tilẹ ni *Akirimanu*, nitotọ ẹnikẹni ti o ba rin jina yio mọ itumọ ohun ti orukọ wọnyi jẹ.

Olugbode jẹ Angẹli iku,
Aboribẹmbẹ jẹ Angẹli Arun
Ọrunmila jẹ Olodumare.

Nitori eyi ko yẹ ki a ma fi oju tinrin nkan ti ara wa, bi o ba ṣe pe Oyinbo kan lo kọ ikọkukọ lasan kan ti a ko mọ itumọ rẹ, iyẹn ni gbogbo wa ma nuri mọ, ju gbogbo rẹ lọ ki Baba Yeye na ma ṣai gbọ adura wa.

Emi ni tinyin nitotọ.
AKIRIMANU.

[Gẹgẹ bi o ti jẹ pe "Ẹru kan lo nmu ni bu igba ẹru," ore wa kan lo sọ ti inu rere ati iwa pẹlẹ ti Wolewole kan hu si awọn ara adugbo kan laipẹ yi nigbati Wolewole na ni lati ṣiṣẹ rẹ lẹhin gbigbe oku ẹniti o ku kan lọ si "Igbalẹ;" a sọ pe gbogbo nkan awọn oni'le na ti nwọn salọ, ni Wolewole yi tọju patapata sinu yara kan ninu ile na ti o si fun omi-ẹrọ si won lori niba; o si jẹ ki awọn ọmọiṣẹ rẹ ko jatijati ti o tun le ko arun ba adugbo na danu; o si fun ogorọ awọn aladugbo na ni "Omi ẹrọ" fun fifi won ile won; ire (*blessing*) ni t'ọmọde t'agba nsu fun Wolewole yi pẹlu awọn ọmọiṣẹ rẹ; a si sọ fun ni pe adugbo ti Wolewole yi hu iwa ọmọluwabi na ko jina si *Branco Street*; l Ojuoto.

A tile tun sọpe Aji-gun-didun-ninu-Ẹṣin ni Ọgbẹni Wolewole na nigbati ilẹ da.

Ti awon Wolewole ti *Akirimanu* nfi ẹjọ wọn sun ilu yi ba le fi iwa jọ Wolewole ti awa papa nsọrọ rẹ labẹ iwe *Akirimanu* yi, bawo ni iba ti dun to? Ed. *Eko Akete.*]


## Springs! Springs!! Gramophone Springs!!!

ALSO

## Isolated Bottles; Vaccum Flasks.

Messrs. Remi Macarthy & Sons, of 5, Taiwo Street, Lagos, has just received a consignment of Springs adapted either for English or German Gramophones. Also (Thermos Bottle) Vaccum Flasks to keep water hot for 24 hours. The Springs and Flasks are sold at very moderate prices. Come and pick yours ere the Stock exhausted. The Flasks are assorted sizes and bodies.

## EKO AKETE.

EKO SATURDAY, SEPT. 20, 1924.

### OGUN BURU, ILU KO DÚN.

Ki a ma tan ara wa jẹ, Ajakalẹ Arun ti o wa ni igboro ilẹ yi lati ọsẹ pupọ sẹhin, ṣẹ ndi ẹru jẹjẹ fun t'ọmọde t'agba; ọwọ-ija ti arun na ka le'ri bi erin, pẹlu ida rẹ, ti o fi nbẹ ẹgbẹrun lulẹ larin wa, nkọ aimọye enia l'ominu ere ni, àwàdà ni, kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀ bùbá kuro l'ẹsọ ere, alabẹrun nd'ẹwu; ero tiwa ati ti ọpọlọpọ enia ni pe, Ebute Awo ti arun na ti sọlẹ si bi Ṣango ni yio mọ; ṣugbọn nisinsinyi o dabi ẹnipe Arun na nfi Onija silẹ, o si nwa gba Alapẹpẹ loju; nitori ẹniti ko mọ ọwọ rẹ lo si mọ ẹsẹ rẹ: k'ari, k'ari, Arun na fo fẹrẹ, o de Idunmagbo, ko tilẹ b'eni b'eji ki o to mu Olorogun lọ; o tun gbe'ra pã o di igboro; o wa'le titi bi ẹniti o ntọwọ b'oku loju, o gbe tasi ija rẹ ko Ọgẹẹni Adamson I. Yakub, Baba Ẹgbẹ awọn Ijọ *Ahmadia* to ngbe apa Ile Disu Koilọ leti Isalẹgangan, ka to ṣẹju pẹ, o sọ di oku bi idan.

Igi ti arun yi npa bi ãra (*Thunder*) nipa atẹhinku ọgọrọ awọn gbajumọ, mu ẹnu ẹni kọ jẹjẹ.

Okiki Arun yi kàn tobẹ gẹ, ti o fi jẹ pe awọn ara wa ni ilu Oke nkandi mọ'le, ti nwọn ko fi jẹ daba lati mu ọja wọn wa s'Eko mọ, tabi ki nwọn wa ra ọja, ogo ni òwò nd'oku, ti owo onjẹ nfo soke, ti idamu ati airoju nfi ara han kakiri; ki Oluwa maṣai dawọ inira yi duro. Ohun ti o ntu ilu, ko ju eyi lọ (k'a ma ri !!!). Nitori titan (*spread*) arun yi, Ijọba sọ awọn Iwe bi ẹdẹgbẹta ti nwọn ti pin kiri fun awọn Bọkinni lati wa fi pade Gomina to de ni ijẹta (*Thursday*) d'oku lẹsẹkẹsẹ, ṣugbọn a mọ pe ko si ohun ti o nle ti kĩ ṙọ; ki Baba maṣai tẹwọgba etutu ti ilu nṣe nisinsinyi. Nitotọ Ọlọrun ju enia lọ, bi ko ba ṣe bẹni lati igbati arun na ti bẹ silẹ, ta lo to duro? Ẹ ko ṣakiyesi ọrọ orin yi :—

Irọ kọ o,
Bi Ṣango ma jo'le
Ti Jaguda ma ja l'ojo
Le-si ma ródo
B'Ọlọrun Oluwa
Ba y'agada le'Ku lọwọ ?

Ta lo to ródo (eyini ni, duro) nigbati Màlékà iku nkọ lálá, bi ẽgun to wa ni Igbàlẹ̀, ti o si nyan fina-fina bi igbati Jagunjagun wọ'lu, ti o npa enia bi mápa l'ọtun l'osi bi Apa-bi ẹkun ?

Ilu, Ẹ jẹ ki a pa lọlọ bi omi, ki a si ba búrũbúrú bi koriko ti ẹ́fũfu lẹ̀lẹ̀ nfẹ titi idanwo yi yio fi rekọja lọ. Ẹ jẹ ki a ronupiwada ẹṣe wa, ki a si sọkun pẹ̀rẹ̀pẹ̀rẹ̀ bi ọmọkekere pe ki Baba ti O nfi ọwọ ọtun rẹ na wa nisinsinyi fun aiṣedede wa, maṣai tun fi ọwọ osi rẹ fa ni mọ'ra.

Lẹkansi, a ki ẹnyin Ilu, Ẹ ku ọ̀fọ̀.

---

[ In view of the 42nd birth-day of our respected Assistant Superintendent of Police Mr. T. I. Kester, which fell on the 16th instant, we have much pleasure in publishing below the Pen picture of the learned Criminal Pros cutor, with the hope it will be of interest to the many friends of the object of our sketch both far and near.

Many happy returns of the auspicious day.

ED.—EKO AKETE ]

### MAN OF THE WEEK.

**TIMOTHY IDOWU KESTER.**

Assistant Superintendent of Police, Lagos: aged 42: born 16th September, 1882: educated first in St. John's School, Arọloya, Lagos, and latterly in C.M.S. Grammar School, Lagos, 1899, joined the Civil Service in the Post Office under the late African Postmaster, George Josephus Cole, as Postman, 1899: was promoted to a 6th Class Clerkship in the Office in question: was transferred to P.W.D. Lagos, 1904: appointed Assistant Superintendent of Police, September 1915: lost his father at Ebute Mẹta, 1909: observed the 20th anniversary of his connection with the Civil Service, May, 1919: is smart, in gait, cultured and "hail-fellow-well-met:" is well read: is Criminal Prosecutor, Police-Court: speaks the King's English with a fluency that can do credit to a Gladstone.




**Kruschen Salts.**
**2/9 a Bottle containing 96 doses.**

HE SINGS IN HIS BATH.

Hard things have been said about the man who sings in his bath, disturbing other people's sleep, but please understand his feelings he is singing out of the pure joy of his heart. He gets up feeling brimful of health and energy, he's glad to be alive, he welcomes the advent of another day of glorious existence, he offers up a song of of praise—even though it's only a music hall song—having been born in such a wonderful world.

Well, that's something to make a song about, ins't it—you who grumble at his musical efforts—you would make music too if you got up feeling as he feels.

And you will feel that way—just bursting with the need of expressing sheer joy of living—if you take your dose of Kruschen Salt.

The little dose that does so much.

Just sufficient to cover a 6d. piece, tasteless in your breakfast cup of Tea or Coffee.

It will keep your kidneys and liver in order, it will remove all waste matter clogging the system, purifying and refreshing the blood, make you tingle in every fibre with new health, new vigour, new joy.

*Obtainable from all Stores and Chemists. Sole importing Agents for Nigeria:* B. ANDERSSON & Co. LTD., *P.O. Box 145, Lagos.*



## H. S. Freeman

Photographer-in-Chief to His Excellency the Governor of Nigeria.

Dealer in all kinds of Photographic Materials

**Films, Post Cards, Views etc., etc, on hand,**

"Also films undertaken for development."

Satisfaction Guaranteed.

*Office*:—106, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

*Telegraphic Address*:—"**FREEDE" LAGOS.**

**P. O. Box 495.**



GBAJARE ỌMỌ-IṢẸ O!

A fẹ Ọmọ-iṣẹ to ja fafa—ibaṣe ọkunrin tabi obinrin niba abọwọde, fun iṣẹ ile. Owo Satide rẹ ko si ni ja.

Niti jijẹ, mimu, ki ẹfọ sa ma diyan rogbo, af'airọ ọ̀jọ̀.

Ẹniti irufẹ iṣẹ yi ba wa lara rẹ ki o wa ri wa ni *Office* "Eko Akete," a o si tẹ lọrun.

## Ẹ WO BI AWỌN ALAGBARA TI NṢUBU!

[ *Wosika lati ọwọ* ATARI-AJANAKU. ]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji,

Bi ere, bi ere, aluba Oko Awo ndi ti gbogbo Ilu, idagiri rẹ si ti sọ ọpọlọpọ ọkunrin di obirin. Bi ẹnikan ti nṣe aisan, bẹni ẹnikeji nku, ti nwọn ngbe ẹni kẹta lọ si Ikoyi. Ti a ba ro ọrọ ti rogbodian ti o wa ni Ilu nisisiyi li ọna ti Ẹsin, a o wipe ẹṣẹ lo mu gbogbo wahala wọnyi wọ ilu. Njẹ bi eyi ba ri bẹ nitotọ, iwa ironupiwada wo ni a o ṣa hu?

Paṣan Ọlọrun nitori ẹṣẹ ni ọpọ enia ka arun ayọkẹlẹ idunfa si, nigbati aluba *Influenza* yi ka 'sẹ ilẹ tan, ti Kọrẹnsi de, iwa ẹṣẹ wo ni awọn ọmọ eriwo ko fi Kọrẹnsi hu tan?

Ọpọlọpọ akin ni *Influenza* sọ di ọlẹ, ọpọlọpọ alaye di oku, ọpọlọpọ ile di ahoro: sibẹsibẹ, ironupiwada ẹṣẹ ko si.

*Influenza* de, o lọ, Kọrẹnsi de, o lọ, Arun Ekute wọ ilu lati Oko Awo. O di ki a mu ko enia lọ si Ikoyi, gbogbo oku di lila, enia ko le koja lọ si Ebute Mẹta lai jẹ wipe nwọn fun Epo Oyinbo ati ohun olorun miran si i lara, ara Ebute Mẹta ti agogo meje alẹ ba lu ba li Eko, Eko ni o ma sun, bẹ gẹgẹ ni agogo meje ko gbọdọ lu bi ara Eko ni Ebute Mẹta, gbogbo nkan di rudurudu bi igbati omi gbigbona dapọ mọ tutu.

Bi nwọn ko Iya pẹlu ọmọ miran lọ si Ikoyi, nigbati Iya miran ba nbọ wa sile, ti a ba bere ọmọ rẹ li o ma to mọ wipe o ti ku sọhun.

Bi Adol Martins ologbe ti jẹ ọkan ninu enia pataki ti o ku ni akoko *Influenza*: bẹni Eko mi titi ni Satide ijẹjọ lati gbọ iku *Chief* Olorogun ti Idumagbo lẹhin amodi ọjọ mẹrin tabi marun.

A fi Sunmọla ologbe jẹ oye Olorogun Onifilafunfun ni ọdun kejila; lati igbana lọ titi ọjọ iku rẹ, ko fi ọrọ ilu ṣire rara. T'ọmọde, t'agba, t'ọkunrin, t'obirin l'o fẹran rẹ, fun igboiya, fun ọyaya, ati fun inu-rere rẹ.

Aye ko si fun wa tobẹ nisisiyi lati sọ ọrọ ti o jọ'ju nipa rẹ, ati lati sọ gbogbo ohun ti a mọ nipa rẹ lati kekere—a fi eyini di ọjọ miran lagbara Baba, a fi eyini di igbati akoko ba to lati sin oku rẹ si Iga rẹ ni Idunmagbo, pẹlu gbogbo iyi, ẹyẹ, etutu ati àṣà to tọ si i gẹgẹ bi Oloye. A ko le daba ati sin i si Iga nisisiyi, nitori aṣọ ṣi ndi egun lọwọ.

Chief Olorogun jẹ ọkan ninu awọn oloye to mura girigiri lati gbe ogun si arun ekute ti nwọn ni o wa lode yi, ṣugbọn "Riro ni enia ṣiṣe ni ti Allah." O bẹrẹ amodi wẹrẹ ni *Monday* tabi atini ijẹtala, o di ẹni ọrun ni Satide ijẹjọ. Nwọn ni arun ekute tabi *Bubonic plague* lo pa a; nitorina, ijọba ranṣẹ fun oku rẹ, nwọn ko si ti i gbe e pada titi di oni oloni.

Laisi ani ani, "iṣẹlẹ" nṣe kiri ilu nisisiyi, iku nlọ siwaju ati siwaju si i. Ọfọ l'ọtun, l'osi; awọn alagbara nṣubu. Ṣugbọn lọwọ ajakalẹ arun gbogbo ati iku ojiji, Oluwa rere gba wa!

## NIGERIAN SPECTATOR, ẸSỌ D'ỌWỌ Ẹ!

Ọro to wa ninu iwe irohin Dr. Savage, *The Nigerian Spectator* ti Satide ijẹjọ ninu eyiti o mu ẹnu kan wa, mu wa ranti itan kukuru kan nipa Ajapa, Aja ati Ẹkun.

Nijọ kan, ajapa kesi aja lati sin on kọja loju-de Ẹkun. Aja ni ṣe ajapa papa mo wipe on ko gbọdọ gba ita Ẹkun kọja, ajapa ni Tô bi àṣà ára Ilọrin. O ni on yio di aja sinu ọkẹ, aja gb' ọjẹgẹ.

Nigbati ajapa di aja sinu ọkẹ tan, o gbe e ru, nigbati o de oju 'de ẹkun, o ni, Họwu, Ẹkun, iwọ ma gọ pupọ o, o ri on ajapa nkọja, o ko le ki on pe o dabọ. Ẹkun dahun o si wipe, ajapa, mo ro pe eṣu nṣe ẹ ni? Ajapa, ni ye e, Ẹkun, eṣu ko ṣe on, ẹru ori on ni eṣu nṣe.

Ẹ jọwọ ẹ ba wa kilọ fun *Nigerian Spectator* ko ma ki ọwọ bọ wa l'ẹnu mọ, bi bẹkọ, a o gẹ e ni ika jẹ, yio ri ẹjẹ ṣoro-ṣoro.

Emi ni tiyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

## "GBA RAN MI HA NṢE ẸLẸRU BI?"

Si Oni'we-irohin *Eko Akete*.

Mo bẹrẹ f'oji o,

Ninu Iwe-irohun *Eleti Ọfẹ* ti ọjọ ketadinlọgbọn oṣu to kọja a ka nipa fifi Ọgbẹni Lawani Ologunro joye Olumẹgbọn si Iga Olumẹgbọn: inu wa dun lọpọlọpọ si eyi—a ki oloye na ku orire—oye a mọ ori o! a pẹ nibẹ!!

Nipari irohin na, a ri ka pe awọn Oni'we-irohin wa ni awọn gbọ pe lati inu Iga Olumẹgbọn ni Adimu ati awọn ẹyọ rẹ ti njade: awa sọ pe eyi ko ri bẹ rara: oloye Ṣagbemi, Igbeṣodi (Oni fila funfun) ti Abegẹdẹ ni o ni Adimu, lati Benin lo ti mu wa lati Iga Igbeṣodi ni Abẹgẹdẹ ni Adimu pẹlu awọn Ẹyọ rẹ ti ma njade ni aiye lailai—nigbati oloye yi papoda ti ko si ni ọmọ ọkunrin agba lati role rẹ ni awọn agbagba ninu awọn ọmọ oloye yi—gbogbo awọn ti nṣe obinrin pinnu lati fi Adimu si ipinmọ oloye Apena Ajasa niwọn ogoji ọdun ọhun, bi agba adugbo ati bi ọrẹ oloye Ṣagbemi ologbe, opopo Ojuolokun kanna nibi ile Ọgbẹni Saka Jojo—sa ni awọn oloye mejeji yi ngbe; lati igbana ni Adimu ti wa lọdọ

wọn; nigbati oloye Ajasa Apena ku, nigbati a ma ṣe Ẹyọ fun, ni Abẹgẹdẹ ni Adimu ati awọn Ẹyọ rẹ ti jade; ṣugbọn lati igbati o ti bọ si ọwọ Maja ọmọ Alaṣẹ Odu aburo baba Lawani Ogunro ati iyekan Apena ni Adimu ti njade lati inu ile Alaṣẹ Odu l'ẹgbẹ Iga Apena awọn Ẹyọ rẹ a si ma jade lati Iga Apena titi fi di Ẹyọ ta ṣe kẹhin ni bi iwọn ọdun mẹfa ọhun. Oloye Lawani Ologunro lo nṣe aṣoju Ọgbẹni Maja ẹgbọn rẹ ẹniti a fi jẹ Akiṣiku to ntọju Adimu nigbana: Maja Akiṣiku ti awọn agbalagba yan yi ngbe Oke-Ipa, ṣugbọn o ti fi ilẹ bora niwọn ọdun mẹrin ọhun.

Ohun ti a fẹ fi ye ara wa nipe Adimu ati awọn Ẹyọ rẹ ki njade ni Iga Olumẹgbọn, bẹni Adimu ki nṣe ti Olumẹgbọn tabi ti Apena bikoṣe ti oloye Igbeṣodi ti Abẹgẹdẹ nibiti o gbe nkansẹ lojojumọ t'a ba nṣe Ẹyọ; awọn ọmọ Abẹgẹdẹ ti mu Ọgbẹni Maja, Lawani Ologunro pẹlu awọn ọmọ Apena lọ si Iga Eleko ni nkan bi ọdun mẹfa ọhun lati gba nkan wọn bọ, awọn oloye Eletu Edibo, Eletu Ijẹbu ologbe, Ọjora ologbe, Olorogun, Ọbanikoro, Oluwa ati awọn agbagba gbogbo lo wa si ipade na—Eleko si ni Alakoso ipade na—nibẹ ni o fi aṣẹ si pe k'a gbe ohun fun olohun; ṣugbọn di isisiyi nwọn koi ṣe bẹ loripe aiya ilu ko balẹ—Laipẹ jọjọ bi oluwarẹ ba fẹ, Adimu yio pada si'le oluwarẹ, aiya ilu ko balẹ ko ni ki onile ma tọju ile rẹ; bẹni ko sọ "Gbaranmidi-ẹlẹru."

A ni tanmọ pe Ọgbẹni Lawani Ologunro niyi to di Ẹni-ọwọ yi ki yio jẹ ka fi ọwọ ro on loju ki nwọn to gbe Adimu fun awọn ọmọ Ṣagbemẹ nirọwọrọsẹ nisisiyi ti nwọn tun ranṣẹ si wọn yi, nitori bi wọn ko ba dapada l'ẹrọ wọn yio da pada l'ele: "Ẹni npe ọ ko dakẹ, o ni o ngbọ agbọya." O ṣe bi owe o! Oluwa ko jẹ ki aiya ilu balẹ fun gbogbo wa o!!

Emi ni tirẹ nitotọ,
IDOGBO.

---

## ADURA FUN AKOKO YI.

*Ki ṣe gbigba nikan ṣugbọn a ni lati hu ni iwa.*

Baba Olodumare, aiyeraiye ati alanu julọ awa ọmọ rẹ alaimore wa nisisinyi si waju rẹ ni irẹlẹ nla ati pẹlu ironupiwada ọkan lati tọrọ anu ati idariji, awa mọ pe awa ti ṣẹ niwaju rẹ o si tọ ka jẹ wa niya—awa nri ẹgba ẹṣẹ wa lojojumọ, a si mọ lara, ni ilẹ wa, yika wa, lẹba wa—awa wa nisisiyi pẹlu ipinnu lati piwada kuro ni iwa buburu si iwa rere awa wa nisisiyi lati pa ofin rẹ ti Olukọni rere ati Olurapada araiye Jesu Kristi kọ wa mọ.

Awọn ẹlẹgbẹ wa ti a ba ṣẹ a bẹ wọn ki wọn foriji wa, awa na si fi oriji awọn ẹlẹgbẹ wa to ṣẹ wa, awa bẹrẹ akọtún iwa lati isisiyi lọ, iwa bi iru eyi ti Oludande ati Olurapada wa fi kọ wa.

"Ifẹ si gbogbo enia, ati ohun gbogbo Ibẹru Ọlọrun yio jẹ ohun ti a o ma tọpa ni gbogbo ero, ọrọ ati iṣe wa gbogbo iwọnyi la wa nbere ni Orukọ Olurapada wa Jesu Kristi, awa si gbagbọ pe Adura wa yio jẹ atẹwọgba lọwọ rẹ nitoripe awa bere rẹ ni igbagbọ nla, awa si gbagbọ pe Ẹ o paṣẹ ki ọwọ ẹgba na da duro, ṣe eyi fun wa Baba Olodumare" aiyeraiye, ati Alanu julọ nitori Jesu Kristi na Oluwa wa. *Amin.*

OTITỌ.

---

Si Ọgbẹni Oni'we-irohin *Eko Akete.*

Alagba,

Alafia kọ ni *Eleti Ọfẹ* wa bi? Obi nikan ni a ti gbọ ri pe o nku si'di ọrọ ọlọrọ, ṣugbọn nisisiyi, a bẹrẹ si ri enia to ngbe ara rẹ ṣaulẹ lori ọrọ ti ko kan lọwọ ti ko kan lẹsẹ. Bi o si ṣepe ṣọbọṣọla na tilẹ mọ ọrọ ọ sọ daradara ni, iba san diẹ, Ṣugbọn gẹgẹ bi afọju to ro pe on le fi jigi tabi *spectacle,* s'oju lati tan enia jẹ pe on ri iran, bẹni ẹniti o kọ iwe nipa awọn Awa-Mọto si *Eleti Ọfẹ* ti ọsẹ to kọja, ninu aimọkan rẹ, o ro pe on nikan lo gbọn ju gbogbo aiye lọ, at Awa-Mọto ati awa Oni-mọto papa nitoripe "Iwe-irohin on dabi atupa to nfi imọlẹ bi ọrọ nkan ti ri han awọn enia to wa ni okunkun."

Nigbati *Eleti Ọfẹ* wipe on ni Iwe-irohin to nfi imọlẹ han awọn enia to wa ninu okunkun, ewo ni ki *Record, Pioneer, African Messenger, Eko Akete, Spectator* ati *Advocate* wi? Tabi awọn talo tilẹ wa ni okunkun ti *Eleti Ọfẹ* nfi imọlẹ han, boya awa Oni-mọto. Ṣiọ! Ẹni a ba ta, ka fi ra atupa; o ni on aji-tan-ina wo l'oru.

Irọ patapata ni *Eleti Ọfẹ* npa nigbati o wipe gbogbo onişẹ Ọba lo nfi ami idanimọ s'aiya; ọrọ omugọ si ni pẹlu lati wipe ko si nkankan ninu ki a fi nkan to jẹ mọ iṣẹ ẹni s'aiya tabi ki a fi k'ọrun. O fẹrẹ le wipe ki akọwe ma gbe aga tabi *chair* ru kiri ilu, nitoripe ori aga lo njoko si kọ iwe, ki *Carpenter* ma so *Hammer* m'ọrun kiri, ki *Painter* ma kun ara rẹ ni ọda dudu ati funfun, ki *Bricklayer* ma fi akaba to ngun mọ ile k'ọrun kiri, ki *Cook* ma gbe iṣasun ọbẹ ru kiri, ki Alapata *Butcher* ma gbe ọmọ Ẹran jo kiri ita nitori ki a le mọ iṣẹ ti nwọn nṣe.

Nigbati *Munisipa* ṣe ofin pe awọn Awa-Mọto yio fi *Badge* k'ọrun, nwọn ha sọ fun wọn pe panu fẹrẹmọ fẹrẹmọ bi agbeji tabi Mọsa Hausa bẹ ni nwọn ma ko fun wọn, awọn Oyinbo papa ha jẹfi iyẹn k'ọrun, nitoripe nwọn nwa Mọto, tabi ijọ ti Oni'we-irohin *Eleti Ọfẹ* papa bi ẹni pa'kurọ ti

## J. C. VAUGHAN

Ti Ile-Oja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Oja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

**ATARI AJANAKU ni OGBENI** na jẹ ninu awọn onişowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ o.

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ṢOLANKE ... "Gbabiọgẹde" nta Pa... (Işika) t'ilẹkun ...kọ, Işo lorişirişi ... Atupa fifalowọ, Simenti, ...ọda lori... ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ... Ọsan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nkọ Ẹja-şawa ...okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ṣọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ.

On si ni aşoju awọn ẹgbẹ Oyinbo onişowo to njẹ Arnold Whitehead Ltd. to wa n Manchester (Ni'lu Oyinbo) to si nranşẹ orişi-rişi ọja fun-ni lat'ọdọ wọn ni Eko ati agbegbe rẹ. Lọ ş'abere ẹhin ọrọ nipa owo yi lọwọ rẹ ni Ṣabu rẹ tabi ki o kọwe ranşẹ si ki o fi şọwọ sinu apoti ikọwe si t'Ọba P.O. Box No. 796, Eko, Nigeria.

### Ẹ WA WO O.

Ọgbẹni E. A. Olemọ ti Ile Işẹ Oluwa, ni 73, Ọdunfa Street, (Anikantamọ) bẹrẹ işẹ agborun titunşe ti baba rẹ nisisiyi. Ọjọ ẹşẹ ti iwọ ati obinrin rẹ ma nsaba ju agborun nyin ti o ba bajẹ nu, Kai! Ọgbẹni kan mbẹ ni adugbo mi ti o mọ işẹ agborun nişişe lọpọlọpọ. Pọ lọwọ rẹ.

## Sabu Ajisefinni.

Gbakan-nşubu orişirişi Ọti *Beer* to jire wa fun tita ni Ṣabu Ibukun Oluwa, Ṣabu Mrs. A. Labinjọ ni No. 28, *Luther* ... leti Mọşalaşi Olosun. S... ...gbogbe (*Cigarettes*) si nbẹ ni... *Lozenges* ati *Pepper*... si ni, pe kami, oworẹ yi ko ... awọn ọja... kam... ...ure tete lọ ra tirẹ nibẹ.

Kai! afara ni'ja Ẹkun.

Cable Address :—
"Steinafrik" HAMBURG

**E. H. STEIN & Co.**

**HAMBURG, Neuerwall 16/18,**
**Hildebrandhaus,**
*AFRICAN MERCHANTS.*

*ALL INDENTS EXECUTED.*
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.
P. O. Box No. 505.

Agent in Lagos :—
**Mr. Karimu Kotun**
3, DOSUNMU STREET.

**Ruby Plates! Ruby Plates!!**
**Ruby Plates!!!**

BOON TO GOLDSMITHS

*Just arrived.*

Call at once and make your choice from :—

DURO THOMAS,
55, Massey Street, Lagos.




*Reduced 3/- each.*

ACCESSORY AND PARTS

**For Bicycles For Motors For Gramophones.**

*ASK FROM*

KADUNA STORES,

79, and 81, Odunfa Street, Lagos

*Near the palatial building of the late Mr. A. W. Thomas.*

And also expert in repairing all.

S. ADE CLAY.

---

Ọgbẹni T. A. Ẹrinoṣo jẹ Ojulowo Oniṣowo. O nfi ọja ranṣẹ, o nta ọja, o si nra ọja, o jẹ Oniṣowo pataki ninu Ekurọ Epo, ati oriṣiriṣi Ọja miran. Ọgbẹni na si tun jẹ ẹniti o gba iwe ati ma ta Ilẹ, Ile tabi Oko.

Ẹ lọ fi Ọja nyin fun u ni:—

19, Opopo Tinubu,

Tabi ki ẹ kọwe si ni:—P.O. Box 242,

Eko.

---

## T. A. Erinosho,

*Forwarding, Shipping, Buying, Selling and Commission Agent, Land and Estate Agent. Produce Merchant, Licensed Auctioneer & Valuer.*

19, Tinubu Street, P.O. Box, 242,

Lagos, Nigeria.

---

## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

---

ILU ẸPẸ KO KERE L'AWO, ẸIYẸ O BA LO GE.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ti No. 88 Ọpopo nla l'Eko nibi ṣeṣẹ ṣi Ile Egbogi to kẹ[illegible]n si eti Ebute l'Ẹpẹ.

Ile Egbog[illegible] ko jina si Ile-Ọja awọn Oyinbo Oniṣowo Jo[illegible] Holt.

Ọgbẹni yi ni Ajẹdolẹru Egbogi ni Ṣabu na, eyiti ki foju arunkarun ba'lẹ gẹrẹ ti a ba ti lo wọn.

Ẹ wa dan a wo: bẹ lẹ o ba.

Ọpọku-ọyọku ni owo tita wọn.

---

B. A. ỌLA SILVA,

**Certificated Typewriter Mechanic**

*5 years Mechanical experience Marine Work Shops.*

Undertakes Repairs of Typewriters, &c., at moderate charges.

*Business Place:*

30, DOHERTY STREET, LAGOS.

**A Trial Solicited.**

---

**Ile Ita Egbogi ti Macaulay,**

88, BROAD STREET.

Wabiwọsi oriṣiriṣi Egbogi lo ṣeṣẹ de fun wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo oriṣiriṣi, ogun Ẹda, ogun arun aṣiri, ogun Arẹmọ, ogun Onigbameji, ogun Aran oriṣiriṣi, ogun Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko le mã to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si jẹ bi idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wọnyi wo nibi ti a gbe nta wọn.


---

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.